Chief Secr. Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 282 SATURDAY, JULY 7, 1928. 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.


NIGERIAN SECRETARIAT 11 JUL 1928 LAGOS


## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by
Victor White, Esq., *Chemist.*
41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

# TO STOP YOUR ACHES & PAINS

## SIMPLY USE




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:
FASSETT & JOHNSON, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

### IMI ẸRAN NI 'DI ENIA.

Irohin kan ni lati Badagry pe awọn ọkọnrin kan lọ si ilu ti a npe ni Mõ ta wọn ti ilu ati orin ni ọganjọ oru lati lọ ja Ọgbẹni kan lole; a gbọ pe dide ti nwọn de ibẹ oporo ibọn ni nwọn dabo ile na tobẹ ti onile na fi ara ṣoko a gbọ pe nigbati awọn igara na ri aya ọkọnrin na nge ni nwọn gba loju ti nwọn si bere ibiti ẹru ọkọ rẹ wa? Ninu rogbodiyan yi ni a gbọ pe ibọn kan ti onile na yin fun idabobo ẹmi rẹ mu awọn ole yi tuka. Ṣugb n nigbẹhin gbẹhin a gbọ pe ọwọ awọn Ọpa Ọba tẹ gbogbo wọn, a si ko wọn wa si Badagry.

### DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

### ỌMỌ LESI YẸN WA?

Ede yi li a fẹrẹ le lo si ẹda-iwe ti a da ni oyinbo ti o mbẹ ni isalẹ iwe yi nipa Onṣẹ-ọba kan ti nwọn ni o lọ halẹ mọ Eleko ni Ọyọ pe nwọn ko ni jẹki o wa si Eko mọ lailai lẹnu rẹ lọhun. Ẹ gbọ labari yi ti wi:—

We understand that an Official Inquiry is being promptly undertaken with a view to ascertain who and who are responsible for the mischievous move on Thursday last when the District Officer at Oyo amd a European Police Officer from Lagos went to Prince Eshugbayi Eleko at his resident in Oyo and there to disturb the innocent Prince's peace, even in exile.

Since Prince Eshugbayi Eleko had been at Oyo on August 8, 1925, the District officer Mr. Reginaled Henry Lapage, B.A., has only once paid the Prince a visit, and that was on horseback in May last, when he chatten to Prince Eshugbayi Eleko over the mud window of his hut, for seven minutes only.

There is a strong presumtion that the mischief last week was hatched from Lagos ; but we do not desire at this or any later stage of the proceedings to embrass the higher officials of the Nigerian Government—L. D. N.—25/6/28.

### MỌṢALAṢI-JIMỌ.

Dajudaju ẹniti o ba ri Mọṣalaṣi Jimọ ni opopo *Victoria*, yio ri gbangba wipe Mọṣalaṣi na kuro ni wasa, Oluwa lo gbe le awọn Ilu lọwọ o dabi Mọṣalaṣi Hadj : Nitorina a le gba awọn Jamat Musulumi ni imọran pe o tọ wipe ki nwọn tun Mọṣalaṣi na ṣi lẹkeji papa bi Ilu ba nranti ore ti Sati ṣe fun wọn ni idunrin—Seriki-gomọ ! Samani-gomọ !!

### KERIA NI TABI GASIKIYA ?

Otitọ ha ni iro ti a gbọ wipe awọn oyinbo oniṣowo kan ngba ṣọbu lọwọ awọn oyinbo Kọra lagbara ni Ibadan, lẹhin igbati o jẹ wipe olukuluku njumọ nṣe iṣẹ tirẹ ni ẹfọ ki isi le ẹfọ lawo ?—o ru wa loju de aiye kan.

### SUDDEN CHECK.

1. The mischievous propaganda which was going the rounds that " the Eleko case will be heard at Oyo and not at Tinubu Square, Lagos, and that Prince Eshugbayi Eleko will never return to Lagos " since the meeting at which Major W. Birrell Gray attended at the Iga Idunganran on Wednesday last,—has suddenly cooled down since the gallant Major's visit to the Iga on Saturday last.

We have not however been favoured with an official denial,—for publication in these columns, —of the rumour we published on Friday last, in justice to the Administrator of this colony.

### THE HOUSE OF DOCEMO.

2. We have been authorized to state that the members of the House of Docemo have withdrawn from Jonathan Collins Zizer, Esquire, Solicitor of the Supereme Court of Nigeria, their insructions empowering him to act a Solicitor in the Eleko case ; and that such withdrawal has been confirm-

ed by Prince Fshugbayi Eleko at Ọyọ on 20th instant—L. D. N,—27/6/28.

ILE DOSUNMU.

A gbọ wipe awọn ẹbi ọmọ'ba Dosunmu ti yọwọ Lọya Zizer (ẹniti a ti mọ ni Lọya Eleko ri) kuro ninu ọran ẹjọ na—lẹhinna a si tun gbọ wipe Eleko papa fun ararẹ ro wipe on ko fẹ ni Lọya on mọ.

IGA ỌLỌTỌ.

A gbọ wipe Kotu fi aṣẹ fun oni-gbanjo kau ti o ṣjẹ Ọlaboye Lalayẹ lati ta IGA ỌLỌTỌ ni ọjọ kọkan-dinlogun oṣu June. nipa ẹjọ ti Lọya Latunde Johnson ba wọn ṣe a si gbọ wipe lọjọ Alaruba to kọja ọjọ 29 oṣu June to kọja na ni nwọn yio ta Iga na—papa gidi ninu Iga yi na ni Oloye omidiji Akọtun ngbe.

THE HOUSE OF DOCEMO.

We are authorized to state that the members of the House of Docemo have instructed Isaac Kushika Robberts, Esquire, Solicitor of the Supereme Court of Nigeria of "Utshi House" 22, Breadfruit Street to act as Solicitor in the Eleko case untill further order.

The Honourable Eric O. Moore, Barrister at Law, of Ijẹmo House, will be the Leading Counsel who will represent Prince Eshugbayi Eleko in presenting the Prince's application for the hearing of his case on its merits, as remitted to the Supereme Court of Nigeria by His MOST EXCELLENT MAJESTY the King upon advice of the Lord of the Judicial Committee of His Majesty's Privy Council —L. D. N—29/6/28.

AWỌN ỌMỌBA DOSUNMU.

A gbọ wipe awọn ọmọba Dosunmu ti fun Lọya Isaac Kushika Robberts ni aṣẹ lati wa fun ẹjọ Eleko nigbati nwọn o ba sọ lu u ni lọlọyi, a si gbọ wipe Lọya Eric. O. Moore ni yio jẹ aṣaju gẹgẹbi ẹniti yio ṣoju ẹjọ Eleko ni Kotu.

LỌYA ZIZER ATI ẸJỌ ELEKO.

Anu ṣe wa gidigidi lati ri bayi pe, gẹgẹbi a ti gbọ wipe Eleko yọ ọwọ Lọya yi kuro ninu ọran ẹjọ rẹ.

Nigbati Ijọba mu Eleko kuro ni ilu, Ologbe Lọya Slyngle ati Lọya Montacute Thompson ni Eleko gbe ẹjọ rẹ le lọwọ, eyiti o nfẹ ki Ijoba sọ iwe-aṣẹ ti nwọn fi mu kuro ni ilu di okibo, ninu rogbodiyan a nṣe ẹjọ yi ni Lọya Zizer de ati larin igba ti a gbọ awọn Lọya iṣaju na ṣe ai mura to mọ si ẹjọ Eleko na.

Nigbati oran da bayi Eleko fi aṣẹ fun Lọya J. C. Zizer lati wa fun u lori ẹjọ tamu-tamu na; Lọya yi bẹrẹsi ba iṣẹ yi bọ titi lori wahala ofin abiasi kọpọsi eyiti nwọn fi si kotu pe ki kotu yọnda fun Eleko lati pada wa si ilu fun mimọ ohun ti on ṣe ki a to wa on ni iṣaṣandidi kuro ni ile ati ni ilu baba on.

Lọya Zizer yi ṣe wabi-wọsi wahala si kotu sidi ọran yi, o si nyọ ọkan-o-jọkan ofin si kotu eyiti o fi nhan kotu pe Eṣugbayi ni ẹtọ gẹgẹ bi ofin Habiasi Kọpọsi lati pada wa si ilu fun mimọ ohun ti o ṣe ki Ijọba to wa on kuro ni ilu lori gbogbo wahala oporo ofin ti a ni Lọya Zizer nda si kotu, agbaregbabọ, okibo ni ẹjọ Eleko mbọ si.

Sibẹsibẹ ko baye ko wo ani ko bikita ani bẹni ko si ṣe arẹ lori iṣẹ ribiribi rẹ ti o nṣe sidi ẹjọ na, otunbọ ntẹra mọ lati ri wipe Ijọba gba ti on ati lati ri wipe on lo jagun ẹjọ na molu—ṣugbọn bi o ti wu ki o ri kotu ko fi igba kan fun ni are ti o nfẹ gba—bayi ati lori wahala iṣẹ ti o nṣe rẹ yi lo bere lọwọ kotu pe on fẹ gbe ẹjọ Eleko lọ si iwaju Prifi Kansulu, lẹhin igbati kotu gbe e ṣanlẹ porongodo; ṣugbọn ko bun u ni iyọnda to tẹrun, bi o ti wu ko ri Lọya Zizer tiraka o jẹ ki ẹjọ na rekọja lọ si ilu oyinbo, titi Ọba (*King*) Alaiyeluwa fi fun Prifi Kansulu laṣẹ lati gbọ riro ẹjọ na lori ẹjọ aroturo (Apili) ti a gbe nihin ranṣẹ si ọhun eyiyi jẹ ọjọ 9 oṣu May, 1927.

Larin igbati ẹjọ yi mbẹ ni ireti gbigbọ ni ilu oyinbo, ni a gbọ wipe awọn ọmọ-ọba Dosunmu ti nwọn wa ni atilẹhin ẹjọ Eleko yọ ọwọ Lọya Zizer kuro ninu ẹjọ Eleko

Nwọn pade ẹjọ arotunro Eleko ni ọjọ 30 oṣu April ati ni oṣu May to lọ yi, eyiti awọn Adajọ fi idajọ wọn pamọ titi o fi di ni ọjọ 19 oṣu June to pari yi ti awọn Onidajọ fi bun Eleko ni are ẹjọ (Apili) rẹ.

Lẹhin ati lori eyi a ko gbọ wipe Lọya Zizer ṣe paramu kan lati ma ba iṣẹ rẹ lọ titi a fi gbọ wipe Eleko pa Lọya Zizer na ti patapata pe on ko fẹ gbọ runmurunmu rẹ nidi ẹjọ on mọ—ọran na wa buaya o le gongo; ṣugbọn kini Lọya Zizer ṣe ti ọran fi da bayi? eyi ko ye ni a si ro wipe bi o ba ṣe a ko ni ṣai gbọ a ko ni ṣai mọ, bi a tilẹ nri ọpọlọpọ awọn enia ti o nkanu fun Lọya Zizer loni nipa ọran na, gẹgẹbi o ti jẹ anu diẹ fun awa ti a nsọrọ yi, nitori sababi ọrọ na koi ye wa to.

THE NIGERIAN PIONEER.

A gbọ wipe Iwe-irohin yi ti o jade ni ọjọ 22 oṣu June to lọ yi sọ wipe o yẹ ki nwọn mu awọn ẹniti o nyọ ayọ are ẹjọ Eleko kiri ilu ki nwọn si kọngọ fun wọn; ti o ba jẹ bayi ni iwe-irohin na wi nitotọ, a fẹ sọ fun u wipe Iwe-irohin na ko ri awọn kan ninu oṣu August ọdun 1925, lẹhin ti Ijọba wa Eleko kuro ni ilu ti awọn ẹniti a nwi yi ni Kiriyo ni Imole ni agba ati ni ọmọde ko onilu-ṣẹkẹrẹ si iwaju ti nwọn nyọ ayọ Eleko ti nwọn mu kuro ni ilu pẹlu orin ọtẹ bayi lẹnu pe:—"Ẹniti ko gbọ tọ'ba yio re ile Ọyọ, awọn ngbọ tọ'ba"? bi ko tilẹ ri wọn ko ni ṣai gbọ labari na—awa ro

wipe Ijọba ko jẹ lọwọ sinu wipe awọn yiomu ẹnikan ntoripe o nyọ ayọ ohun ti oluwarẹ lẹ ni iwọn igbati oluwarẹ ko ba ti di alafia-ilu ṭlọwọ—itiju pamiare epe !

## IWE-IROHIN IJỌBA.

A gbọ wipe Iwe-irohin Ijọba *The Nigerian Gazette* ti ọjọ kerinla oṣu June 1928, sọ wipe Onikoyi-oko *The Secretary of State* ṣe ifohunsi ṣiṣe iwe owo titun ti ilẹ enia dudu *West African Currency Note* oni 20/- ati 10/-, nwọn si sọ gẹgẹbi ami ara iwe na yio ti ri—a ro wipe lori eyi bayi Sati le ṣi ilẹkun asiki fun gbogbo ẹniti airi ṣẹṣe ti pa rọ sile lati ọjọ gbọrọ ; awa si le gba Ijọba Gẹsi ni imọran lori eyi pe, iba dara julọ bi nwọn ba tun le ṣe oni 2/- ati 1/- bi ti aiijọ, ki nwọn si ṣe oni 6d kun pẹlu ki o le wulo daradara fun nina dipo owo ṣile papa ti ilu nlo lọwolọwo yi ; amọran ni o ! a ko fi paṣẹ ki Ọba *King* pẹ titi.

## NIGERIAN DAILY TIMES.

Iwe irohin yi ti o jade ni ọjọ 30 oṣu June, 1928, sọ wipe ọrọbansa ni irohin ọrọ Ipade ti iwe ni nwọn ṣe ni Iga Ọbanikoro ( Adamo Akẹju ) jasi nipa ikilọ fun awọn ẹmẹwa rẹ lori dide Eleko lati Ọyọ, eyiti Iwe irohin *Lagos Daily News* sọ ni 29/6/28, ati wipe iwe irchin na nwa owo lati gba lọwọ awọn enia ni, a si sọ wipe aṣoju iwe awọn yio mura lati gbọ gasikiya ipade ti iwe wi yi lati ọdọ Oloye Ọbanikoro—lẹhinna o si fi ẹnu ẹgan ati ti tẹmbẹlẹkun darukọ Ọba wa Eleko sinu iwe ti ko ṣanfani fun awọn enia dudu bikoṣe awọn oyinbo nikan.

Ọrọ omugo ati afojudi li eyi jẹ fun wọn, a si ro wipe ipata enia ati ẹniti enia ko kun loju lo sọrọ sinu iwe *Daily Times*, a o mareti iwe irohin yi fun yẹkini ọrọ ipade na eyiti o ni awọn yio gbọ gan leru lati ọwọ Ọbanikoro gẹgẹ bi labari ti iwe irohin *Daily News* fi han ilu, a si tanma wipe ko jẹ ri bẹ - dajudaju !

## IWE-IROHIN "WEST AFRICA"

Gbogbo ilu kun fun ireti iwe-irohin yi ti o njade ni ilu oyinbo nisisiyi lati mọ bi Idajọ-Apili Eleko ti lọ si ni kikun, eyti awọn ogunna-gbongbo mẹta da ni ọjọ kọkandin-logun oṣu June, 1928

Ọkọ "*Apapa*" eyi ti o dide ni ilu oyinbo ni ọjọ Alaruba ijẹrin ( 4.7.28, ) ni ilu nreti iwe-irohin *West Africa* na ninu rẹ, a si ro wipe dide ọko na yio jẹ ọjọ Alamisi ọjọ 19 oṣu yi, eyiti o ku ọjọ mẹtala si loni.

## THE HOUSE OF DOCEMO.

King Dosunmu, who ceded the Island of Lagos, died in 1884, when he was succeeded by his son Oyekan, who died in 1900, and was succeeded in 1901, by Eshugbayi Eleko, another son of king Dosunmu.

In this Extraordinary Gazette there is now published for the first time (1920) a despatch dated 23rd February, 1901, and addressed by the late Sir William Mac Gregor, a former Governor of Lagos, to the Right Honourable Joseph Chamberlain, then His Majesty's Principal Secretary of State for the Colonies —J. F.—P.5.

## LEMỌMU MỌMỌ DABIRI.

Gbukẹ li a gbọ ti iku Lemọmu Mọmọ Dabiri ni owurọ ojo Atalata ijarun, eyiti o ṣẹlẹ ni ile rẹ ( Ọbadina Street ) ẹniti a mọ ri ni Lemọmu awọn Alalukurani, ti o tun pada di Lemọmu awọn Ijọ Ahmadyya ni iwọn ẹdun mẹfa tabi meje sẹhin, nwọn sin oku rẹ si Mọṣalaṣi Jimọ ti Arọlọya Street. Ki Ọlọrun Ọba dẹlẹ fun u o.

## JAMAT MUSULUMI.

Awọn Jamat Musulumi ṣe ipade wọn ni ile-iṣẹ *Administrator of the Colony*, ni Alaruba ijẹrin nipa ọran oku awọn Musulumi ti awọn Municipal ngbe yẹwo; eyiti a gbọ wipe ọga awọn Municipal wa ninu ipade na—A tanma pe a o tẹ labari ọran na pẹlu ọrọ wa lọṣẹ to mbọ.

---

## IROHIN AWỌN IGBIMỌ ALATUNṢE ỌBA ALAPẸRU ỌLỌLA.

Nipa ija to wa larin Madam Odumusi ọmọ Ọba Alapẹru ati Ẹfunyẹla ọmọ Alagbe ti Ẹjina Iperu town o dabi ẹni pe Ẹfunyẹla nfẹ da ija silẹ ni Ile Ọba Alapẹru Ọlọla opẹlọpẹ awọn Igbimọ Ọlọla nla Lemo, Opẹlẹ, Apena, Ajayi, Jonu, Ọgbẹni Ọpẹodu, Ọgbẹni O. Shobodu, awọn Alatunṣe Ile Ọba Alapẹru ni yen, awọn ti wọn mu Ẹfunyẹla jade kuro ninu Ile Ọba Alapẹru ọrọ na bi Ọgbẹni Akilesi Likọtun Ọlọla aburo Baba wa ninu pupọ tobẹ gẹ ti o fi wa sọ ni ile wipe nkan ṣe loni ni o ọ keji Ẹfunyẹla gbe atẹ aṣọ lọ kiri de Agbole Olugoke, nigbana ni Madam Oyebade sọ fun Madam Ẹfunyẹla pe on ko fẹ ki o tun de Agbole baba on mọ nitori o mu ohun ibinu wa si arin wa pupọ ki Ọlọrun Oluwa Olodumare ki o pẹlu Alapẹru ati awọn Igbimọ ati gbogbo ilu.

J. A. O. SHOMADE.

---

## IWE LATI ỌDỌ J. A. SHOMADE SI IJỌBA GẸSI NI EKO.

Mo bẹbẹ mo si fi oribalẹ fun ẹnyin Ijọba Igesi nipa ọran owo ṣile ti awọn Ijẹbu nṣe ọna ti Ijọba Igẹsi fi le kawọ awọn Ijẹbu ti o nṣe owo ṣile ni yi. Afi bi Ijọba Igẹsi le ran awọn Private tabi aṣiri Detective tabi Ọlọpa Inu ranṣẹ si Ijẹbu Rẹmọ ati nigbogbo agbegbe Ijẹbu Ode ki awọn Ọlọpa Inu

yẹn ma wọ gbogbo Ile Agbẹdẹ ki awọn Ijọba Igẹsi jọwọ ba wa ma parọ awọn Ọlọpa Inu na ni ọsọsẹ ẹ ma jẹki ẹnikẹni ni Ile Aṣiri tabi ibi aṣiri rara nipa ọkan Agbẹdẹ ṣile ti wọn nṣe ni ilẹ Ijẹbu yio kakuro ni ilẹ wa bamubamu tabi patapata.

J. A. O. SHOMADE.

---

*AFIYESI PATAKI*:—Ni ọsẹ to mbọ ni agbara Soko, ao ṣe Wosika pataki kan lori iṣẹ ribi-ribi ti Ọgbẹni Habati Makọli nṣe nipa ọran Ile-Dosunmu, ẹ maṣe jẹki iwe ọsẹ to mbọ nu nyin.

KEKERE AWO.

---

It pays to advertise in
"EKO AKETE"
The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## ẸNYIN AWA MỌTO Ẹ RỌRA.

[ LATI ỌWỌ OGIDAN ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Anu ṣe ni purọ pe bi awọn Ijọba ti nda sẹriya to yi fun awọn awa-mọto wọnyi, o dabi ẹnipe loju mi nwọn ko bikita arara.

Ni alẹ ọjọ *Saturday* ti o kọja yi, bi a ti mbọ ni iwọn dede agogo meje-abọ lati *Ebute Mela*, bẹni a ri oni-mọto kan mbọ lati Eko, bẹ gẹgẹ si ni ni oni-kẹkẹ-ologere mbọ pẹlu, bi ko si ti Oluwa ti o pe ṣiṣe ọdọmọkunrin yi tun ku l'aiye ni, inu omi ni ko ba ba ara rẹ, lati ori Kereni Idọ. Pataki ohun ti a fẹ tọ ka si fun awọn awa-motọ na ni pe, oju ko tilẹ nti wọn ni, oni, igbe awa-mọto, ọla, igbe awa-mọto, nijọwo li ẹ o ye ninu iwakiwa nyin o dabi ẹnipe nwọn ma ngbagbe pe arin Ilu ni awọn gbe nwa mọto, ẹ lọ sun kaka ki ẹ si ronu iye gbajumọ ati taiaka ti ẹ ti ran lọ s'ọrun apapa ndodo nipa iwakiwa nyin, omiran ninu nwọn nigbati nwọn ba nlọ si *Ebute Mela* nwọn a ri gbangba-gbangba pe mọto kan wa niwaju wọn nibiti iyẹn gbe nlọ kẹlẹkẹlẹ jẹjẹ ara rẹ, ṣugbọn ara ile mi nkọ, pẹlu jigi ni igi imu, a fẹ ṣe fari loju Salamọtu pe o mọ mọto yi wa ju ẹniti o nlọ niwaju on yẹn lọ, sisare lo ma sare gba ẹgbẹ ti iwaju yi kọja bi ẹni nsare ẹṣin l'ọdan, ti o si ma ṣiwaju rẹ, kini a le pe iyẹn nisisiyi, ti o ba lọ fi bẹ ṣe jamba ti ọwọ awọn Ọpa Ọba ba tẹ ẹ, bi ṣiṣe ni nwọn gba iwe rẹ lọwọ rẹ ni o, awa ma fi ẹnu jẹ kakiri wayi o, a ni on ko ri iṣẹ ṣe, ngbọ nigbati o ri iṣẹ ṣe nkọ, nṣe nkọ lo nṣe ni iṣekuṣe? Bi ko si ọkanna, ọrọ ti "Asalu" sọ fun nyin ninn *Eleti-Ọfẹ* ko ti to ki ẹ sun kaka ki ẹ ronu, ngbọ ẹ sa mọ ju ọka tọrọ ati ẹran sisi lọ. ẹ pẹlẹ o, ọmọ-ijẹka, ọmọ-isọta, oye ti ẹ sa gba niyẹn nisisiyi.

Omiran ninu awọn awa-motọ wọnyi ti o gbagbe ara rẹ patapata, ti o jẹ pe ṣakaṣaka ti nwọn da pẹlu mọto na ti papọju, mo bere lọwọ yin melo-melo ninu nyin ti o jẹ pe ọfẹ li o nfi mọto gbe awọn obinrin lọ sibikibi ti nwọn ba fẹ, bẹni nkan kan sa ni oni-mọto sa ma gba dandan-ndan, ko so si ohun ti o nlọ l'ọfẹ l'aiye isisiyi, omiran ninu nwọn, lẹhin ti nwọn ba ti mu wọn lọ si ibiti nwọn ba fẹ tan, o di rẹrẹ lọna okun, mo tun bi nyin kini ọdọmọbinrin ha nlọ ta lọna okun loru? Ki iyoku ma ro ki ninu nyin. Ẹnyin obinrin onirinkurin, a ya bara si eyi, lati fi han ẹniti o nsọ pe. "Ọmọ-Awo" fẹran lati ma yọlu awọn obinrin pupọ ju, bi okun fẹ bi ko fẹ, ẹsa rin ọ sọna okun niwọn agogo mẹwa alẹ ẹ o ri ariṣa awọn ọmọ yin nibẹ, pẹlu awọn awa-mọto wọnyi, tabi bi bẹkọ ki ẹlọ wo wọn lọdọ awọn Kuku tabi awọn Agbawo Oyinbo ni ọsan niwọn bi agogo mejila-abọ mọ agogo kan, pataki awọn obinrin ti nwọn ni awọn kiri ọja; ju

gbogbo rẹ lọ, a bẹ awọn oni-mọtọ papa ki nwọn jọwọ ṣe kilọkilọ fun awọn onikẹkẹ wọn.

Nkan pataki kan latun fẹ fi siwaju awọn oni-motọ wọnyi (*car owners*) pe, Tinubu de Ebute Mẹta tabi Ebute Mẹta de Tinubu ni kan ko ni asiki wa, nwọn tun le ma gba enia ni iye kan kanna lati Tinubu de Ikoyi tabi Sagọrọsi tabi lati Sagọrọsi de Tinubu, tabi bi bẹkọ lati Tinubu de Odo Mosisi, ati lọna ibomiran bẹbẹ, mo ro pe nipa ṣiṣe bẹ mọto yio tun ta siwaju ju pe ki gbogbo nyin rọri si Ita Tinubu de Ebute Mẹta nikan lọ, ti ija si ma nde nigbakugba larin awọn awa mọto pe, ero mi ni, ero rẹ kọ, ẹnyin oni-mọto (*car owners*) ẹ gbayi yẹwo o.

A si tun fẹ fi ṣe kilọkilọ fun awọn awa-mọto pe nwọn ngbagbe bi a ti ran wọn, lọ, o yẹ ki nwọn ni itẹlọrun pẹlu owo iṣẹ wọn, ko dede ti a fi sọ bẹ ni ọjọ isimi to kọja obinrin kan fẹ wọ mọto lati Ita Akanni lọ si Idita, awa mọto na ni bi obinrin yi ko ba le san ṣile mẹwa-abọ ki o ba ẹṣẹ rẹ sọrọ, bẹ la ha ran nyin bi? Ẹsọ ko d'ọwọ nyin pẹlu iwakiwa, kilo kuku ṣe, bi obinrin tilẹ jẹ Millioner iba kọ lo ma sanwo fun awa mọto mọ, bẹni o da mi loju pe, gbogbo wa la mọ ibiti obinrin gba bimọ ki a to ni ki o kẹhin si,na.

Ti awọn ara Eko li asọ yi, mel li a o ka ninu awọn awa-mọto ti ọna oko, ẹjẹ enia li awọnyẹn ṣa fi nrin lojojumọ.

Ni ipari gbogbo rẹ, a bẹ nyin l'orukọ Oluwa ki ẹ rọra pẹlu iṣẹ nyin o. Bi ẹko ba gbọ a o ni ye ma ki ipọri ọkọ fun ọkọ.

Emi ni tinyin nitotọ,
OGIDAN.

---

## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## NWỌN NGE NYIN LỌWỌ, Ẹ NBỌ ORUKA.

APA KERIN.

Emi ri ọpọlọpọ iya ti o jẹ wipe ọmọ wọn wa ni ile ọkọ kan, sibẹsibẹ ti nwọ tun ngba ọmọ wọn ni imọran pe esu ọwọ kan ko ma to ko, o maṣe da nidi ti ẹnti o ni on nfẹ ọ, ki i ma nṣe aiye tirẹ nikan lo wa, ọmọ wo lo ma gbọ irufẹ ẹkọ bẹ ti ko ni gbe igba apamọ dani lati ma ṣe "awọlujẹ" kiri? mo bere irufe ẹjọ wo ni awọn obi bẹ ma ri lọrun? nitori ọna ibajẹ ni nwọn tọ ori ọmọ wọn si.

Obi miran wa bi oju ko ba ka mu daradara o frẹrẹ le pe ọmọ bibi inu rẹ lati ba huwa agbere, nigbati iwa yi ba ti di ẹti si ni igba-aiya tan ti ko si le fi silẹ ani nigbati o ba ti di onjẹ ajẹmọnu fun wọn tan, bawo ni irufẹ awọn obi bẹ ti ṣe le ni ẹtọ lati kilọ iwa buburu kan fun awọn ọmọ wọn, ni ọna mejeji ti a la silẹ yi?

A hale sọ wipe irufẹ Ajakalẹ-arun ti o ja ni ilu wa ni ọdun kẹwa (1918) laṣeko Ogun Ajakaiye ti o pa ọkẹ aimọye Ọmọ Anabi Adamọ ati kakiri aiye papa ni arin ilẹ yi ati eyiti o ṣi nja lọwọlọwọ nihin (ti a si mbẹ Oluwa ki o dawọ ibinu Rẹ duro) ha jẹ ti a le yara gbagbe? Tabi kilo nya apari ti o nmokun lodo—a ko ṣai nranti iye enia ti arun Ajakalẹ npa bi danga lọdọdun ti awọn Ijọba ba ṣiro iye oku to ku fun ọdun kan lati inu ọdun 1924 ọdun kerin ohun ti aisan Arun-Ekute ti wọ'lu ti o si ni on ko ni lọ mọ ki isi wọ inu ilẹ ki o maṣe sọ idunnu kalẹ sinu ile na, ki a maṣe sọ ohun miran.

Awọn Ijọba ṣa agbara won titi nwọn na ọpọlọpọ owo ki arun buruku na fi le kuro ni ilu sibẹsibẹ pabo, bi o ba dawọ duro diẹ, bi o ba tun ṣe yio tun ṣọlẹ si adugbo kan bi Ṣango, ti o bi si gbija ni adugbo na bi igbati epo *Petrol* gbija ninu ina ni, a si ni lati ri wipe o tun adugbo na ṣe daradara fun wọn ki Ọlọrun ma jẹki a sọ wipe o baajẹ fun wọn ki o to dawọ duro, ẹ ko wa ri gbangba dajudaju pe Ọlọrun lo mbinu si wa fun kini o? Fun itori ẹṣẹ wa, ọna ti a si ngba da ẹṣẹ si Ọlọrun na ọkan ninu rẹ li a nsọ yi, njẹ bi nwọn ti nge ọmọ Eko lọwọ bẹkọ ni nwọn si tun mbọ oruka, pẹlu bi a ti nsọ fun wọn yi na kọ ni nwọn tun nhuwa aibikita nipa ohun ti a nsọ yi.

Pẹlu bi a ti ni Ajakalẹ-Arun nyọ ilu lẹnu yi bẹni Kọrọnti nko igbaiya ba ọpọlọpọ tobẹ ti a fi le sọ wipe boya ẹyiyi na nṣe atilẹhin iku fun ọlomiran, eni Kọrọnti, ọla Kọrọnti ọtunla Ilefinfin gbogbo rẹ di rudurudu, ẹ o ri wipe ohun ti Ọlọrun fẹ pẹlu wa ni.

(*Koi pari*)

ỌMỌ-ILU.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, JULY 7, 1928.

## PRINCE EŞUGBAYI ELEKO NTA BI OŞUMARE.

Lati nkan bi ọsẹ mẹta ti gbogbo Ilu ti gbọ pe Prince, Eşugbayi Eloko jare Apil rẹ ni Kotu Abesẹ Ọba King ni Ilu Oyinbo ni gbogbo Eko ti ntu yẹyẹ titi o fi de Ilu Oke ati Oke Okun: kosi ẹniti ko mọ ifẹ nla nla ti ẹgbagbeje enia ni si Ẹni Ayọ nfẹ na: bira ti gbogbo Eko da lọjọ ti waya de, papa ere ti aimọye awọn obinrin şe yi igboro ka ko ni şai fi han Ijọba pe lotoloto ifẹ ti ilu ni si Prince Eşugbayi Eleko jasi ifẹ ti ki iku: a si mọ pe ayọ yi pọ gidigidi lode Ọyọ nigbati Ẹni wa na gbọ iro ayọ ati inudidun yi kodede ti nkan fi ri bayi bikoşe pe yiyan ti a yan Eleko ki o rọpo Oyekan ẹgbọn rẹ lọjọ pupọ sẹhin jẹ yiyan ti ko ti ọwọ on papa wa. Eyini ni pe ko bẹbẹ joye ati ọna ti awọn kan ngba fi şi nipo pada jẹ ọna ti aiye kọ ti ọrun si kọ pẹlu, ori Eleko jẹ ori oye lati ode ọrun wa: awọn ti nwọn tilẹ jẹ ọta rẹ tabi ti nwọn nba şe kokowa ko ni şai jẹwọ ni kọrọ yara won, pe ni gasikia ẹniti Ọlọrun da ti ko şe farawe ni Prince Eşugbayi Eleko jẹ: kurumọ ni, o, Aganyin ni o, Şẹkiri ni o kosi ẹniti ko yọ ayọ ayọmọju lọjọ ti Waya ribiribi na de: gidipa Iwe Irohin kan ti o lodi si ni lati jẹwọ pe awọn obinrin ko na ita lọjọ ti a nwi yi.

A ko le şeşẹ tun ma sọ bi Waya ti ba awọn miran lojiji ti o si jẹ ohun ti o ya won lẹnu gidigidi: bẹni işẹ Olodumare ni, bi awọn kan ti pe yio ri; ko ri bẹ mọ.

Ẹ o şakiyesi pe a ki ye tẹnumọ lọjọ pupọ sẹhin pe kosi bi ayọ na ko ti nipọ to ni igboro ilẹ yi lọjọ ti ilu ba gbọ pe Eleko jare: a woye pe ọrọ wa na şẹ. Lode oni a tanma pe nipasẹ ọrọ Eleko, o ti di Koriko ti o ni ki erin ma goke alọ yio di alọmọlẹ lẹsẹ erin. Talo gbọdọ jẹ ku moyọ tan ko ni on yio sọ isọkusọ? Talo gbọdọ jẹ ọşẹ ko fi ogiri fọşọ?

Ki a sọ ti gasikia kosi ipa kipa ti awọn kan le tun sa lati yọ irawọ Eleko lẹnu mọ; tita ti oşumare rẹ nta nisisiyi dun mọ gbogbo araye ninu ti ẹlẹgan loku, eyi kole şe ki o ma ri bẹ nitori ilu ko le wa ti awọn kan ma mu odidi Ọba rẹ lọ si ilu okere ki ilu na si gbọ pe Ọba na tu mbọ wa si le ti inu ẹnikẹni ko ni dun, afi inu awọn agbẹhin bẹbọjẹ okiki aşọ ti olukuluku adugbo nda silẹ fun ọjọ pipade rẹ kan wa, a si mọ pe ojulowo ayọ ati inudidun ni yio gbodekan ni ọjọ yi. Talo le jiyan pe ori okiki ni ori Eleko jẹ? Ijare ti o tun ju eyi lo di şaşa nitoripe ko si ẹniti ọran na kodunmọ lomode lagbalagba ni ilẹ yi ati nkakiri *Nigeria*.

Ọrọ Ọba wa Eleko tobẹ o jubẹlọ ti a ba nro ti iwa alufaşa ti awọn kan filọ, şugbọn ọpẹ lo yẹ Ọbangiji Ọba ogo fun işẹgun nlanla ti are jijẹ yi mu wa fun gbogbo wa agbọnrandun rẹ.

**Eleko Ọba ni!!!**

---

### GBOGBO ẸYIN EKIMOGUN ARA IJAMỌ TO MBỌ L'EKO Ẹ GBARADI.

Oşemọwe Ọba Ondo nfẹ gba Ade ni ọjọ *Tuesday* ọjọ kẹwa oşu yi ni Ode Ondo, nitorina a ti ikede yi sọfun olukuluku ọmọ Ondo to mbẹ nilẹyi lati gbaradi ati lọ sile lati ba Ọba wa na şe ẹyẹ kẹnkẹkẹnkẹ yi.

A o ma jihin Igbade na fun ẹnyin ara wa yoku ti ẹja tutu Eko ko fun laye lati le yọdi lọ si'le.

## ỌGBỌN ỌDUNNI WERE ẸMI.

[ Lati ọwọ Ọkanṣọṣọ Ajanaku. ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ko jẹ ifẹ inu wa lati ma mu ọrọ Ọba wa sọ lore-lore, kikoṣe ti ọran pataki-pataki ba ndelẹ bi eyiti ẹnyin na yio ti ri tabi ti gbọ okodoro dajudaju ki a to fọ sinu iwe fun nyin ka; ohun ti a fẹ ki a mọ loni ni wipe pupọ enia li o wa li ode aiye ti ẹmi ifarada (endurance) ti jinna si pupọ bi Sanma ati ilẹ ti jinna sirawọn, kini ohun ti o njẹ ẹmi ifarada ti a wi nisisiyi ẹ jẹ ki nla ye nyin, on le wipe, ti enia ba nfẹ nkankan lọdọ Ọlọrun nisisiyi ti o ba nfi ojojumọ tọrọ nkan yi pẹlu mimọ ọkan Ọlọrun yio ma timọ wipe nkan ti ẹni yi ntọrọ o jẹ ẹdun ọkan fun gidigidi, ti ko ba si tete dalohun ohun ti o nfẹ yi, yio ma jẹ ibanujẹ ọkan fun lojoju ṣugbọn nipa ọkan mimọ ti o fi ntọrọ nkan yi, Oluwa yio fẹ lati danwo bi yio ni ẹmi ifarada fun ohun ti o nfẹ na, ṣugbọn ti oluwarẹ ba jaja le fi suru fun ẹmi rẹ bi o ti wu ki o pẹ dandan Oluwa ki yio ṣai dalohun, ṣugbọn ti enia ko ba li ẹmi ifarada, ti o ni ṣe mo tilẹ fi ojojumọ gbadura gbadura ni Mọṣalaṣi tabi ni Ṣọṣi agara tilẹ da mi on ko ri nkanna ko ni igbagbọ si Ọlọrun niyẹn.

Apẹrẹ pupọ lo wa lori ọrọ ti a nsọ yi nipa pe ki enia ma fi tọkantọkan gbadura ki o si ni ẹmi, ifarada, ti o si jẹ wipe o ti ni anfani tabi ọwọ rẹ ti tẹ nkan ti o nfẹ li atẹtan ti o jẹ wipe ati aromọdọmọ rẹ li yio ma jẹ anfani rẹ lo titi, nko le ma la oniruru ohun bẹ fun nyin nisisiyi, ṣugbọn bi o ti wu ki o ri, Baba Oke lori agbara Rẹ, ko ni ṣai fun mi li ọrọ sọ nijọ kan ṣa lati la ọpọlọpọ apẹrẹ lori ọrọ yi fun nyin.

Gẹgẹbi mo ti wi soke pe ọgbọn ọdunni were ẹmi; kini ha tiṣe ti o jẹ wipe ẹlomiran ti de aiye o fẹrẹ to ọmọ adọrin ọdun tabi ju bẹ lọ, ti ọgbọn ati lakaye ti parẹ mọ ninu, ti omugọ na le fẹrẹ sọ ẹlomi di were ọsan gangan, mo ti nka ẹlomiran kun ọlọgbọn pataki ri larin ilẹ yi, ṣugbọn nigbati ọran Eleko wa delẹ, mo ri ọpọlọpọ awa ara Eko yi li ariṣa pe aṣiwere ati olori omugọ gba a patapata li ẹlomiran ninu wa, aṣe bi nkan ko ba delẹ bayi, a ki imọ apọda ati akidani-dani enia omiran, ti a o si ma ro wipe ọlọgbọn pataki kan li o nṣe, bi ailowo lọwọ tabi nkan miran li o tilẹ nsọ ẹlomiran di iranmu ni ko ye ni arara.

Ẹni ti ko sa bọti ki ibẹru ojo, e ha tiṣe ti o jẹ wipe lati igbati Eleko ko ti si nilẹ yi ti awọn ọbaiyejẹ ilu ba ti dani nkankan silẹ, yala nwọn pupọ tan ara wọn jẹ ni tabi nwọn nsọ ododo fun ara wọn ni, o di wipe ki ẹlomiran ma wohinwọhun ki o si ma kọ ọ ominu, ti omugẹ ni, tabi ti ailowo lọwọ, ẹ ma duro na, ailowo lọwọ yi yio ma sọ ẹlomiran di were ọsan gangan larin ilẹ yi ni 'wo ti mo nwo yi; nigbati nwọn tilẹ ti itori ọpa koṣe ọpa ti Gomina Kilifọdu da Eleko duro, ti ilu si duro ti lẹhin timotimọ, ẹwẹ ti ina ẹgbẹ awọn kau njo, ko da mi loju pe omugọ ẹlomiran nilẹ yi ti nwọn ni lẹhin Eleko li awọn duro si pọ to bi ti isisiyi, nigbati a wi na, o ha tọ si ẹlomiran ti o ni ire ilu li on nfẹ tabi ti o nfowọ sọ'ya konko pe lẹhin Eṣugbayi Eleko li on wa girigiri, ti o si di ọjọ oni ti nwọn nmokun logbẹ ilẹ kiri, irufẹ ṣiṣe bayi ha tọ si ẹniti a bi're hanunhanun, mo ṣebi ti adanwo ba nde ba enia bayi li a ma nmọ ẹniti o nfẹ ni tọkantọkan, a ko sọ ti awọn ti o npe Eleko ni tẹgbọn taburo awọn? Ani lara awa ilu ti a jumọ fowo sọwọ-pọ nijọkini pe bi Sanma tilẹ nya bọ lẹhin rẹ li a wa, enia li o ma mọ oni kẹ o, boya ọsin ti o gbe alumọ lọ, tun le gbe bọ lọju ẹmi olukuluku.

Nitotọ enia ma nsaba tẹ s'ibiti aiye ba gbe tẹ si, ṣugbọn ki iṣe bi iru ti Ọba Eleko, tani ha le sọ gbangba ninu ẹnyin ti ẹ nforu boju kiri (ti ẹ ko mọ wipe awodi oke ti ri nyin) wipe Eṣugbayi Eleko sun iṣu oro fun nyin jẹ, ọmọ atiro ti o ba si fẹ gun agere o nfẹ gbọ ọrọ ni, bi eyiti a si nawọ le yi ko si igbati a ko ni ṣai ṣe bẹ? Ani Eleko ti ilu nja fun ki iṣe fun ara rẹ nikan, ki isi ṣe nitori rẹ li ilu tiṣe da ẹgbẹ Democratic silẹ gẹgẹbi awọn ope miran ti nwi nigba kan, fun ire ilu gbogbo ilẹ enia dudu ti a si ntẹnumọ wipe nitorina o yẹ ki a ṣe ẹgbẹ nilu; aye ko si tobẹ fun wa lasiko yi, nba gbiyanju lati la yekeyeke nitori ko ye ẹlomi tobẹ arara pẹlu, nko si ni ṣai ṣe bẹ laipẹ ọjọ, ọgbọn ọdunni were ẹmi ti a wi yi abọ ọrọ lo jẹ fun ẹniti o ba mọ wipe iakaye wa lori on nitotọ ti ki iṣe edidarẹ bi a ti nwo si i tabi ti nwọn tilẹ npe ẹlomiran gan. Lakotan ọrọ mi, ẹnikẹni ti nwọn ba fori rẹ sọlẹ silẹ yi tabi ti nwọn tilẹ fi omi Eko yi rọ dagba gbaanran, ti owo ba si nda lamu ti ko si duro si ori iwọn rẹ, ti o ba ni iwa aitọmọ li on yio ma hu, pataki, ti o ba ni on ba onile jẹ, ba onile ma tan, o di ọjọ bayi o ni on yio yẹri, iṣonile ni, iṣ'alejo ni, iṣọmọ Ọba ni, iṣejoye ni, tabi-tabi ko si nibẹ oluwarẹ pẹlu Sanma ati ilẹ di karewa.

Emi ni tiyin nitotọ,

ỌKANṢỌṢỌ AJANAKU.

---

ORI IV.

## IṢẸ.

( *Translated from " Character by Dr. Smiles "* ).

APA KẸRIN.

Lord Stanley (ti o wa di Earl of Derby nisisinyi) ni o sọ ni Glasgow pe :—

"Emi ko gba pe enia ti ko ni iṣẹ ni ayọ to totọ ri, tabi pe ole ni ayọ totọ lailai, biotiwu ki oluwa rẹ ṣe enia to tabi ki iwa rẹ dara to. Bi iṣẹ ti jẹ ẹmi enia to, bi iwọ ba fi iṣẹ ti o le ṣe han mi, emi o si sọ fun ọ iru enia ti o jẹ. Mo ti sọ nipa ti pe ki enia ni ifẹ si iṣẹ ti o nṣe jẹ ohun ti yio gba kalẹ kuro lọwọ iwa-kiwa. Ju eyi lọ mo si tun le sọ pe eyi tun jẹ ohun ti ngba ni lọwọ awọn aniyan pẹ-pẹpẹ ati lọwọ ikannu eyiti iwa anikan-jọpọn imu wa.

Ki o to to oni ni awọn ẹnia a ma ro pe ti nwọn ba da do ti nwọn ko ba ba ẹnikan pa, awọn yio bọ lọwọ iyọnu ati ikannu. Nwọn ti dan eyi wo nigba pupọ, bakanna si ni o nku si. Enia ko le bọ lọwọ aniyan ati lala iṣẹ—bi aiye ti ri nun....Awọn ẹniti bi iyọnu ba de ti nwọn aṣe ojo ti nwọn a salọ, nwọn a ri i pe iyọnu awa wọn kan. Ọlẹ enia le lo ọgbọn ki o jẹ pe iwọn iba diẹ ninu iṣẹ ti a pin fun laiye ni o ṣe; ṣugbọn Ẹlẹda ti o ti mọ iwọn iṣẹ ti o yẹ fun olukuluku ẹda ti o si pin bẹ, a mu ki iba diẹ ti ọlẹ enia ṣe na ki o pọ ki o si nira loju rẹ.

Enia ti ko ni oriṣa miran ti o bọ ju ara rẹ lọ, bi o pẹ titi, ko tilẹ ni pẹ boya, ki o to mọ pe oluwa nla ni on yan; bẹ si ni ojo panyanun ti o nyẹ iṣẹ ti o tọ fun lati ṣe silẹ, ni iya tirẹ pẹlu, nitoripe bi a ba kọ iṣẹ pataki ti iṣe tẹni silẹ laiṣe, awọn okun ti ko to nkan a di nkan pataki, a lo danu lasan lori ikannu ahumọ iru eyi ti i ma bi ti iṣi ma rẹ si ninu alaini ero enia."

Ani, niti ọna ti o kere julọ gba—ti igbadun ara ẹni—o yẹ ki ọwọ ma dilẹ nigba-kugba. Enia ti ko ṣe iṣẹ ko le gbadun ere iṣẹ.

Sir Walter Scott ni:—

"Awa a sun a sun tagiri nipa, awa gbadun asiko ti a wa ni ojufo nitoriti ọwọ wa ko di lẹ; ki a ri iṣẹ kan ṣe ni mu ni gbadun isimi, biotilẹ jẹ pe iṣẹ wa na jẹ ti ọkọ kiko lẹhin eyiti isimi tọ si ni."

Lotọ ni iṣẹ aṣegan a pa awọn ẹlomiran, ṣugbọn awọn ti iwa anikanjọpọn, aiye ijẹkujẹ ati iwa ọlẹ npa ni o pọ ju. Bi a ba ri ti iṣẹ-asegan ba ṣe enia lọṣẹ, ohun ti o mu wa ju ni aimọ aiye lo bi o ti tọ ati aibojuto awọn ọna wọnni ti ara fi nle. Lord Stanley ko ṣiṣẹ boya, nınu awọn ti o nkọ ni Glasgow sọ eyiti a ti mu ẹnu kan ni iṣiwaju, nigbati o sọ pe ko da on loju bi "iṣẹ pupọ tabi iṣẹ lile, bi enia ba tẹpa mọ ti o nṣe lọ laisọṣẹ, ṣe ẹnikan lọṣẹ ri."

Ẹwẹ, ẹmi gigun kọ ni o tọ ki a fi ṣiro bi enia ti pẹ laiye to. Iṣẹ ti enia ṣe ati bi o ti mọ aiye to ni a le fi diwọn bi igbesi aiye rẹ ti to. Bi iṣẹ rere enia ba ti to; bi o ba ti lo oye ori rẹ ti o si mọ aiye to, bẹni igba ti o ṣe laiye to. Ọlẹ enia ti ko ni anfani kan lara bi o ti wu ki o pẹ laiye to, kan wa gbunduku ni.

Awọn ti o kọkọ kọ ni ni ẹsin kristi, nipa iwa wọn nkọn pe iṣẹ ṣiṣe ni nkan nla. Saint Paul ni:—

"Ẹniti ko ba ṣe iṣẹ ko tọ ki o jẹun;" on papa si taka si pe on fi ọwọ on ṣe iṣẹ, ati pe ẹnikan ko da owo fun on."

Nigbati St. Boniface gunlẹ ni Britain, ti on ti iwe ihin rere lọwọ kan ati irin iṣẹ gbẹna-gbẹna lọwọ keji ni; lẹhin na ni o ti England rekọja lọ si Germany, nibiti o gbe ṣe iṣẹ ile kikọ. Luther papa, bi o ti jẹ pe ọwọ rẹ ko dilẹ lọna miran to, sibẹ o nṣe iṣẹ jẹun o nṣe ọgbın, o nkọ ile, o nṣe agogo

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## *Olusakin's Column.*

LUNCHEON PARTY AT THE BONANZA HOTEL.

On Saturday afternoon, the 30th June last, Mr. & Mrs. Henry Carr gave a luncheon party in honour of Sir Kitoyi Ajasa, Kt., O.B.E., at the Bonanza Hotel at which about 50 guests were present. Sir Kitoyi is a Government Nominee in the Nigeria Legislative Council, representing Colony Division.

THE HONOURABLE S. J. FOSTER.

We are pleased to record that the Honourable Mr. Samuel John Foster, M.A., B.C.L., M.B.E., of

Bathurst Gambia has been appointed to act as Magistrate of the Colony of the Gambia. Our Congratulations.

Nigeria! Please copy this noble example for the good of our country and race.

ST. JOHN'S LODGE NO. 2668, E.C.

**Installation of Worshipful Brother Hon. S. H. Pearse.**

The Hon. Samuel Herbert Pearse, F.R.G.S., was installed the Worshipful Master of St. John's Lodge, No. 2668, E.C., on Monday evening, the 25th June, 1928, at St. George's Hall. Congrat.

MRS. E. M. BLAND.

Mrs. E. M. Bland, wife of the generally popular Manager of the Nigerian Railway, has had a serious Operation, and her friends at Home and in West Africa will glad to know that it has been successful, and she is in this countiy making a good recovery.

In the list of successful candidates in the Continuous Course Examinations, for students for the Irish Bar, at the King's Inns, Dublin, published on June 7, the name of Mr. Ọmọsanya Adefolu appears. Mr. Adefolu received third-class honours. *West Africa, 16/6/28.*

LORD TERRINGTON.

**Sentenced at the Old Bailey.**

Lord Terrington has been sentenced at the Old Bailey to four years penal servitude.—*Reuter.*

The Lord Terrington was charged under the Larceny Act for Fraudulent Conversion while practising as a solicitor. The amount involved is reported to be about £70,000.

BIRTH.

We congratulate Mrs. Druscilla Ẹniọla Coker, wife of Mr. Richmond Olawunmi Coker of Victoria Street, Lagos, for safe delivery of a female child on Saturday, the 23rd June, 1928. Ki Oluwa ko da ọmọ si.

ON LEAVE.

Mr. L. O. S. Morafa, Assistant Station Master, Kakuri, is now on one month's *vacation* leave as from the 21st June 1928. Mr. Morafa arrived Ijebu-Ode on the 23rd June 1928, to spend the leave with his family before resuming his duties.

DEATH OF IMAM MỌMỌ DABIRI.

The death is announced on Tuesday morning the 3rd July, 1928, at 3. a.m. of Imam Momo Baidhu Dabiri of the Al-Koranic Section of Lagos and of the Ahmadia movement.

The interment took place at Arọlọya Mosque at 5 p.m. the same afternoon. Our sympathy.

OLUṢAKIN.


INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## We are sole local Agents for

# Vibrona

*The Ideal Tonic Wine.*

---

SURPASSES ALL OTHER WINES

AS A

## TONIC STIMULANT

AND

## INVIGORANT.

**VIBRONA** has been justly described as the **Supreme Tonic**, and the world-wide reputation which it enjoys is mainly due to the personal testimony of those who, having experienced its remarkable energising powers, are glad to recommend it to their friends.

A liqueur-glass of VIBRONA, taken either alone or with a plain biscuit, is almost magical in its effect as a Tonic Restorative.

---

The modern Discovery for Female sufferers is

## Wireless Female Pills

A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against harreness. 4/6 per bottle of 72 Pills.

## Kaduna Balm 1/-

The family Remedy applicable in 100 different ways. Indispensable during this rainy season.

## Saccharine 1/-, 1/6

## Anti-Rhumatic Salt 2/- and 3/6

## Rheumatism Pills 1/6

## Yaro (*small and large*) 2/3 & 3/3

## Pile Pills 1/6

## Pile Remedy 7/6

## Cooling Blood Purifier 7/6d.

(A powerful blood cleansing Preparation).

## Gonorhea Remedy 7/6 & 4/6.

Works with effective rapidity.

***Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2. 2. 0.***

Special Wholesale Price.

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109 Griffith Street, Ebute-Metta.

## Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications.

Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

## Attention! Attention!! Attention!!!

FOR BUYERS IN GENERAL

HAVE YOU BEEN AT

# IWA-JO-WA STORE, (No. 1 & No. 2)

IF NOT, WHY NOT? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else-where.

The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby!**

( *Again and again, "Gbangba dẹkun" Kedere bẹ wo.* )

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scissorses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
" " Alum,
" " Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.
Seeing is believing;

"*Ganni ya fi ji.*" Irohin ko to afojuba.

Apply to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street. Isalẹgangan, Lagos,
20, Victori Street, Lagos.

*Cable Address :—*
**Iwajowa Store No. 1,**
45, Princes Street, Lagos.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

RẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS ".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.